# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.


## Owe

Ina fi Ikoko Ṣawa o ngba kurukuru S'omi.

Abinueni ko ri koto tini si. Ohun ti Ọlọrun yio ṣe ko fi han Ẹnikan.

## AKIYESI

Olotu "Iwe Irohin Imole" yio ba Oko Ofurufu pada de si Eko ni Ọjọru 18/7/62. Awon ọpọ Ola-Ilẹ wa yio hesel ma a jade ninu Iwe Irohin Imole. Aimọ ina tete ranse Sii ti e ki o ma ba kabamo.

Enyin ti e wa ni Mushin ati agbegbe rẹ, Ẹ̀ ri Irohin Imole ra ni 24, Olyede Street, Odo-Abore, Mushin.


VOL. VI No. 337 MONDAY JULY 16 — JULY 22 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


# GBỌMỌGBỌMỌ SỌ ỌMỌ ILE-IWE KAN DI ODI

EKO:— AGBOSOGBANU NI IROHIN ỌMỌ ILE-IWE KAN, ABIỌDUN AHMED, ENI ODUN MERINDINLOGUN TI O ṢE AGBAKO GBỌMỌGBỌMỌ KAN NIGATI O NLỌ SI ILE-IWE NI OWURỌ OJỌ OJỌ'RU TI IṢE OJỌ KỌKANLA OṢU YI, GBỌMỌGBỌMỌ NA SI SỌ Ọ DI ODI PATAPATA.

Irohin ti awọn Ọlọpa ṣe fun awọn Oniwe Irohin wa nipa iṣẹlẹ na ni pe, bi Abiọdun Ahmed ti nfi ẹsẹ rin lọ si Ile-iwe, ni Ọkunrin kan wa mọto ba a loju ọna, o si sọ pe ki o jẹki on gbe e lọfẹ lọ si Ile-iwe rẹ. Abiọdun si wọ mọto na. Lẹsẹkẹsẹ ti ọkunrin na ṣi mọto rẹ, ọna Idi-Oro ni o kọrisi, o si mu Abiọdun wọ inu ile kan ni adugbo na. Lẹsẹkẹsẹ ti o mu u wọle ni o ba gbọn egbogi kan le e lori Abiọdun ko si le sọrọ mọ, ko si ranti ohunkohun ati awọn Obi rẹ mọ pẹlu ile ti o ti jade.

Nigbati awọn mu ọmọ na de Teṣan awọn Ọlọpa Ebute-Metta, ọwọ ara rẹ ni o fi nkọ Irohin gẹgẹbi ọkunrin Onimọto na ti ṣe mu u lọ si Idi-Oro, ṣugbọn ko ranti orukọ ara rẹ ati ti awọn Obi rẹ mọ.

Nigbati Baba ọmọ binrin na, Alhaji Ahmed reti pe ki ọmọ rẹ dari wa sile lati Ile-iwe, ti ko si ri i ti ti ilọ fi ṣu, ni o ba lọ si Teṣan awọn Ọlọpa l'Ebute-Metta lati fi ọrọ na sun awọn Ọlọpa, o si ba ọmọ rẹ Abiọdun nibẹ, ti o ti diti ti o si yadi patapata.



ALHAJI AHMED BABA ABIỌDUN



IYAAFIN AHMED IYA ABIỌDUN

Lẹsẹkanna ni Alhaji Ahmed ati Iyawo rẹ ba mu Abiọdun lọ si Ile Babalawo kan ni Idi Araba fun iwosan. Nigbati nwọn de ọdọ Babalawo na ti o si gbọ ohun ti o ṣelẹ si ọmọ na, lẹsẹkẹsẹ ni o wọle ti o si mu nkan jade fun Abiọdun lati mu Nigbati abiọdun mu egbogi na oju rẹ wale wọ e, ṣugbọn ko le sọrọ.

Nigbati Abiọdun sun, ti oju rẹ si walẹ ni Babalawo na ba tun fun ni nkan miran lati lo lọsẹkẹsẹ ni Abiọdun si bẹrẹsi sọrọ ṣugbọn ko ti le sọrọ daada. Ṣugbọn o ti nṣe alaye bi awọn kan ti ṣe ba ni ọna ti o si sọ pe ki o jẹki on gbe e lọfẹ lọ si Ile-iwe rẹ

Abiọdun Ahmed yio sọ Irohin bi on ti ṣe salọ mọ awọn gbọmọgbọmọ na lọwọ ninu Iwe Irohin Imọlẹ ọsẹ ti mbọ tete ranṣẹ fun ti ẹ ki o ma ba kabamọ.

---

Ẹ MAA KA IWE IROHIN IMỌLẸ NIGBA GBOGBO.



Aworan ti e nwo loke yi ni ti Omidan Abiọdun Ahmed nigbati o njade bo lati inu Tesan awon Olopa ni Ebuta-Metta.

---


## MO TUN GBE DE O!

Idije Orire Ponun kan Sile kan (£1 : 1/-) yio jade ninu "IWE IROHIN IMOLE" ose ti mbo.

Anfani nlanla leyi! Tete ra Iwe Irohin Imole lose ti mbo ki o si gba (£1 : 1/-) tire.

## ỌRỌ OLOTU

### Bikoṣe pe Oluwa ba pa ilu mọ, awọn Oluṣọ ji Lasan

GBOGBO ENYIN ỌMỌ KARỌ, O JIRE NI AWA ONIWE "IROHIN IMỌLẸ" NBA WI LOSE YI. Yio dara fun gbogbo awọn omo Yoruba kakiri Agbaiye lati ri wipe ki a gbe ADURA Atata dide psape si Ipinle Iwo - Orun wa yi, ti o je pe on nikan ni gbogbo awa omo kn Ootu, o jire, gbe oju le pe, ki Olorun Oba ti o ni Aiye ati Orun mase jeki o bo lowo awa omo Yoruba, nitoripe ti abere ba bo lowo Adete o de gbe segee.

A wa be oyin pupo ki gbogbo awon Olu ati Ijoye jake jado ile Yoruba se eto gidigidi lati le mu bi awon yio tise gbe adura yi dide laipe jojo pe ki Olorun ninu anu Re jowo mage binu si wa ati wipe ki O jowo tete ba da anu Re pada s'orile ede wa ti rogbodiyan mbe ninuyi.

Awa Oniwe "Irohin Imole" mo daju pe, ti a ba si ki a mase wadi pe enia kan lo jere tabi enia kan lo jebi a titan ara wa je ni titi odun meji ti edekoyede yi yio ma lo siwaju ati siwa'u si ni ti a ko ni ri idi otito ninu re.

Nitoripe ko si enikan nino awon ti o uja yi ti yio so pe on ko fi ara ko ninu rogbodiyan ti o wa ni ile yi. Ti a ba si so pe a imadi re lo titi Eru yio tobo ti ere lo omi gbigbona. Ipinle Iwo orun yio si bo sowo awon ota.

Nitori idi eyi, awa oniwe "Irohin Imole" keri enyin Agbagba Omode Orile ati mekunnu pe ki a pasapo ki a gbe adura atata dide Ki awon Oba ati awon Ijoye ipinle yi si nin ba wa fi ori bon Anbe gbe etutu atata dide kiakia. Nitoripe Agbalagba ki wa loja ki ori Omo tuntun o wo, Gbogbo Agbaiye ti bere si wo wa ni awosokun, sugbon a awo ara wa lawoerrin.

Olorun duro de wa lati gbo adura wa, nitorina ki Musulumi, Kiriyo, Aborisa Kerubu ati Serafu ya ojo merin gedegbe soto fun adura Akanse.

OKUNRIN KAN LU ỌLỌPA META E O MA KA NINU IWE IROHIN IMOLE OSE TI O MBỌ

## Ekute ile paramọ Ologini tajo,de!

Alhaji Tafawa Balewa Alakoso Igbimo Apapo Ijoba Naijiria, ti o ti gba isinmi lo si ile re,pada si Eko ni Ojo Ojobo ti ise ojo kejila osu yi.

Alhaji Balewa so fun awon Oniwe Irohin nigbati oko Reluwe ti o wo duro ni Kaduna wipe, on yio se gege mewa fun awon omo ile Naijiria ti nwon lo si Ghana lati lo padipo, ti nwon si mba otuko Orile-ede Naijiria je kakiri.



Alhaji Balewa tun so wipe on gbagbo pe otito ni awon Ara Ghana mba Ile Naijiria je gegebi Ogbeni Jaja Wachuku ti ise Minista fun awon Ile Okere ti so wipe awon Aganyin nse ayonuso si oro Ile wa ti ko kan won.

O ni ki Olukuluku enia gbo ti ara re ko si ohun ti o kan Ile Ghana lati ma a dasi oro Ile wa.

## Ọmọ ilewe kan wẹwọn oṣu meji

IBADAN:- Awon Olopa mu Odaran kan Olorukọ Deiii ti yio jade ni ile iwe (Secondary Modern School) ni odun yi wa si iwaju Adajo Kotu Ijoba Ibile Ibadan ni Ojo'Ru ti ise ojo konkanla osu yi fun esun Ole jija.

Ejo ti Olopa ti o ba odaran n'ejo ro niwaju Adajo ni wipe, Odaran na ji awon aso ogbeni Johnson Oluyide ti o ngbe Salvation Army Road, Ibadan. Iye owo pipon aso na si je pontun meje (£7)

Nigbati Odaran na rojo ti o si gba wipe on jebi ni Adajo ba ni ki o lo si Ewon osu meji lafarabara.

## YẸYẸNATU!
### O ni yẹyẹ Eko

Yẹyẹnatu:— Olotu, Ṣebi ẹni ibukun ni fun onilaja.

Olotu:— Yes kẹ, ntori ọmọ Olọrun lao ma pe.

Yẹyẹnatu:— Ha! ha! ha! Ibukun wo wa ni Rotimi Williams ngba, tabi ki i ṣe ija lo la ni?

Olotu:— Yes ija ni kẹ. O jọ ya pẹnu rẹ mọ Ijọba ko ma gbọdọ gbọ.

Yẹyẹnatu:— Kini, ṣe Ijọba to tun ti i mọ'e lẹhin ti kotu ti da silẹ. He, ejọ yin, ṣe mo ti sọ pe Ijọba gọ.

Olotu:— Mo nsọ fun rẹ Yẹyẹnatu, ṣọra rẹ.

Yẹyẹnatu:— Lotọ ni. Ti Ijọba ko ba gọ ni nwọn a tun jẹ ki obinrin to dara ma ṣe Olọpa.



Olotu:— Kini ṣe kẹ?

Yẹyẹnatu:— Ti ẹ ba wa ni Yaba lalẹ ana ni, anu obirin Olọpa yẹn a ṣe nyin gan ni.

Olotu:— Họwu! Ṣe ntoripe ojo npa?

Yẹyẹnatu:— Ha! to ba jẹ iyẹn ni, ki ba dara. Mọto kan lo ralu u.

Olotu:— Ha! ha! Ṣe bi mọto le ralu Olọpa ọkunrin na.

Yẹyẹnatu:— Ko si irọ nibẹ. Ṣugbọn ohun ti dẹrẹba mọto na wi ni pe, ọdọ obinrin Olọpa yẹn lọkan on wa.

Olotu:— Lo ba ralu u.

Yẹyẹnatu:— Lo ba ralu u bamubamu.

Olotu:— Yè! O maṣe o, Ṣe ko ku?

Yẹyẹnatu:— Ko ku, ṣugbọn o ṣeṣe pupọ.

Olotu:— Kini Onimọto wa wi?

Yẹyẹnatu:— O ni bi o ba ku, on yio pa ara on, Ti ko ba si ku on yio pa ara on ti ko ba fẹ on.

Olotu:— Ha! ha! Ko ni Iyawo nile ni?

Yẹyẹnatu:— Iyẹn ni pe ẹnyin na ko ni Iyawo nile lẹṣe nsare le ọrẹ mi?.

Olotu:— Ṣe o mọ pe iyẹn yatọ.

Yẹyẹnatu:— Kini iyatọ?

Olotu:— Ṣe bi o mọ pe ọrẹ rẹ nwọkọ ni.

Yẹyẹnatu:— Ṣe nwọn sọ pe Olọpa ko wọkọ ni?

Olotu:— Nwọn ko gbọdọ lọkọ ni kẹ.

Yẹyẹnatu:— Ha! ha! Ṣebi Olọpa Ọkunrin ni Iyawo

Olotu:— Yes kẹ.

Yẹyẹnatu:— Hẹ! Ani Omugọ ni Ijọba wọnyi.

Olotu:— Ma lọ, ma lọ, ma ko ba mi. Epo ni mo ru.

Yẹyẹnatu:- O dabọ o. Ojo Ọkunrin.


## Akiyesi Pataki

UNITED BRETHREN PRAYER GROUP. EGBE FẸ ẸNIKEJI RẸ GẸGẸBI ARA RẸ

Eyiti opolopo enia mo si "THE WHITE BROTHERHOOD LODGE".



Njẹ iwọ ha mọ ohun ti agbara adura jẹ bi? Tabi o ha ti gbọ iṣẹ ribiribi ti Ẹgbẹ oke yi nṣe fun ẹniti o ba wa ninu idamu, t'owa ninu aiye bi ẹnipe ko si l'aye. Lọrọ kan, kọwe si Akọwe Ẹgbẹ oke yi fun iwe alaye pipe nipa Ẹgbẹ yi.

**Secretary**
**Box 64, Yaba Nigeria.**


Ẹ MA KA IWE IROHIN IMỌLẸ TI O KUN FUN ORIṢIRIṢI ITAN ALADUN LỌSỌSẸ

# IWE SI OLOTU

## ỌWỌ ỌKỌ LO TI WA

Olotu/

Jọwọ gba mi laye lati dahun ibere kan ti Olotọ Obinrin bere ninu iwe "Irohin Imọle" ọjọ keji osu keje ọdun yi (2/7/62).

Ibere na ni wipe nigbati Ọkunrin kan ba ni iyawo lọna, ti ko ti de ile rẹ nwọn yió fẹran ara wọn. Ifẹ awọn miran a ma a pọ to bẹ gẹ ẹ ti o jẹ wipe ti nwọn ko ba ri ara wọn ni ọjọ kan nwon ko le sun.

Loju temi, Olotu, owo Ọkunrin ni nkan na ti ma a nwa. Nigbati nwon ba nlo si odo won, Ọkunrin yio ma ṣe ileri fun obinrin, awon nkan ti ko ni le ṣe fun ati awon nkan ti ko ni, yio so wipe on ni won lowo, lero wipe ti on ba so be e obinrin yio feran on.

Ṣugbon nigbati obinrin ba de ile re tan ti ko si ri gbogbo awon nkan na ma, ife re yio ma a kuro lodo ọkọ re, ija ojojumo a si wade larin awon mejeji.

Nitorina, loju temi ejo Ọko ti nwon ki i le gbenu won lowo ni oro na ti wa, ki ṣe lati odo awon obinrin.

A bo mi re o.

Emi ni

ALUFA R. A. ỌLỌRUNLOGBỌN

EKO.

## MO KI ỌGBẸNI AFỌLABI ỌJẸLABI

Ẹ jọwọ gba mi laye lati ki Ogbẹni Afọlabi Ọjẹlabi fun ọrọ ijinlẹ ti o maa nfi kọ wa ninu "Iwe Irohin Imọlẹ" lọsẹọsẹ. Awọn ọrọ na kun fun ọgbọn, ẹkọ, oye ati lakaye.

Ki Ọlọrun turbọ ma a fun ni lakaye si ki o si le ma kọ ọrọ na fun awa ọnkawe na ki a le ma a ka a.

Emi ni

MARY ẸBUN ỌLAWEPỌ

Esiẹ–Ọffa

## Ẹ ran wa lọwọ

Inu mi yio dun bi Olotu iwe "Irohin Imole" ba le gba mi laye lati kesi Ijoba Apapo Naijiria lati tun titi Idi-oro Alakija ṣe nitoripe Ọna na ko dara rara, awon ero - Oko ki i gbadun mo ti nwon ba tide ibe, siso ni moto ima a gbe won so soke - sosodo, ti yio si ma a fi ori awon ero inu moto lu pako, Ọpolopọ enia ti ara won le ko si ni ni alafia mo ki nwon to sokale, nwon a si ma a fi omi gbigbona mora nigbati nwon ba dele.

A o dupẹ bi Ijoba rere na ba le tete ba wa tun oju Ọna na ṣe.

Olotu mo dupe aye ti e gba mi, Ọko Ọba ko ni ẹa ayin lese o.

Emi ni

ADEKUNLE ADENIJI

MUṢHIN

## Iwe si awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Olotu/

Gba mi laye lati ṣe ibere meji wonyi lodo awon Ọmu Egbe Imole Aiye. Nitoripe Ọmode logbon, Agbalagba logbon la fi da ile Ife, ibere na niwonyi:-

1. Ese ti nwon fi upe Sule ni Agenjo?
2. Kini idi re ti nwon fi npe Salami ni Agbaje?

Emi ni

JAMES JOHN

GHANA

# IFẸ LOJU (APA KẸRINLA)

LATI ỌWỌ:— Afolabi Olabimtan

Bi o si tilẹ jẹ pe Ojogẹ ko bikita fun obinrin kan, awọn obinrin bẹrẹsi ṣe gbẹnti larin ara wọn. Ọtun ngbiyanju lati jẹ enia loju Ojogẹ. Osi ngbiyanju lati fa oju Baba Bọlaji mọra, gbogbo irohin wọnyi lo nde ọdọ Muli. Ṣugbọn igbẹkẹle to ni si Ọkọ rẹ ko jẹ ko bikita. O ti ni igbẹkẹle pe Ojogẹ ko le gbe Iyawo miran laisọ fun on.

Ṣugbọn ninu awọn obinrin to nda Ojogẹ laamu ni Adunni wa, ni toto Adunni dara lọmọ, o yẹ ni niwaju, o si yẹ ni lẹhin. Baba ati Iya rẹ jẹ Olowo, ile wọn si to marun ni ilu. Iyawo ko kọ pe ki o maṣe ni Iyawo keji, ṣugbọn o fẹ ki Ọkọ on jẹki on mọ ko to gbe de ile. Ọmọ yi, Adunni, fẹran Ojogẹ pupọ, bẹni Baba Iyabọ na si fi nifẹ si. Nikukuru o sọ fun pe on yio fẹ. O si jẹwọ fun pe on ti ni Iyawo, ṣugbọn boya o gbagbe ko sọ fun pe on ni ọmọ. Kẹrẹkẹrẹ nwọn nba ọrọ wọn bọ, o tun nsọ iwa osi, o si nsọ ti ọtun.

Adunni ni Igbona ara pupọ, o si jẹ ẹnikan to fẹ ti ara rẹ nikan. Nigbati o pẹ diẹ ti on ati Ojogẹ ti nba ọrọ wọn bọ, Ojogẹ wọ Ọkọ o lọ sọ fun Iyawo rẹ Muli nipa rẹ. Iyawo rẹ ko kọ, o si lọwọ si, nigbati Ojogẹ npada, Iya Iyabọ fi ẹran ranṣẹ si Adunni.

Ko pẹ lẹhin ti Ojogẹ wa sile, Muli ro wipe o yẹ ki on lọ ki Ọkọ on ati pẹlu lati ri Iyawo titun ti o ṣẹṣẹ nfẹ, ko ranṣẹ tẹlẹ, o kan yọ si Ojogẹ lairo tẹlẹ.

Bi o si ṣe wọle, o ki Ọkọ rẹ, nwọn joko, ko pẹ pupọ o lọ wẹ, bi o si ti wẹ tan, on ati Ọkọ rẹ bẹrẹsi jẹun. Ni akoko yi Adunni wọle. Bi o tilẹ jẹ pe Muli ko mọ Adunni tẹlẹ, sibẹ o kii daradara, ṣugbọn imu ni Adunni fi dahun, ara ta Ojogẹ, ṣugbọn ati on ati Muli ko si ẹniti o sọrọ fun igba diẹ.

Muli ko pẹ ki o to ba ogun na jẹ, o ni "Sisi mi, ẹ mba wa ja ni? ti a si pe nyin wa jẹun ti ẹ ko wa? Ẹ jẹ ki a jijọ jẹ kẹ" Ojogẹ si dahun pe, fi silẹ ti o ba fẹ jẹ ni ki ba ti joko. Eyi bi Adunni ninu, nitoripe o ti ro pe ayanfẹ miran ti Ojogẹ ni, ni o mba jẹun, ko mọ pe Iyawo Ojogẹ ni, ẹran owu ara rẹ ti sọ di enia kekere, o si da Ojogẹ lohun o ni. Nko ba ọ wi, awọn ti nwọn wa nka ọmọle ni, awọn Iya ti nwọn ko mọ ara wọn ni agba, ẹjọ rẹ ko, a soju wa sa o.

Eyi bi Ojogẹ ninu pupọ nitori Muli tobi pupọ lọwọ rẹ, Ife ti o ni si Muli si pọ tobẹ ti ko le gba ki ẹnikẹni ma sọrọ buruku si.

Ẹ O MA KA APA KEDOGUN ITAN MI YI LỌSẸ TO MBỌ LAGBARA ODUDUWA. O DI GBA KAN NA O.

# Oloye Festus Okoti-Eboh mba awọn Oṣelu Mid-West sọrọ



Ẹniti a nwo ni iduro ti o nsọrọ yi ni Oloye Festus Okotie-Eboh nigbati o ko awọn Oṣelu diẹ jọ ti nwọn nba ara wọn jiroro nipa Mid-West ni apa ilẹ Benin. Nwọn ṣepade na ninu ile ẹgbẹ J. K. Randle Hall Diẹ ninu awọn enia to mbẹ nibi Ipade na ni, Senator M. A. Ejaife, T. A. Salubi aṣoju fun awọn ile ẹkọ ati A. Y. Eke Onirohin Ijọba.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Abọdẹrin ninu Igbo Mapẹran (Apa 9)

LATI ỌWỌ:— ABDULAHI A. AWẸLẸNJE

No. 1, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ibiti aba Itan wa na de ni ibiti a ti mba irinke-rindo wa lọ si Igbo iyanu na. Ni dede agogo mẹjọ alẹ ọjọ na ni a yọ si Igbo yi, a ṣe lọjọ yi ni ọjọ Ipade awọn ẹranko ibẹ. Ha! iṣẹ ọwọ Ọlọrun ko lo nka, iṣẹ ọwọ Ọlọrun ko ma ṣo sọ ni ye o.

Bi a ti yọ sibẹ ni mo ti tẹ awọn iyoku mi lẹsẹ ti a si ti mura giri gẹgẹbi ogboju Ọdẹ, a ti tamọra. Bi oṣupa si ti ran ko tilẹ jẹki a mọ wipe ilẹ ṣu rara nitori ketekete ni a nri ara wa, laipẹ a bẹrẹsi ti a p ẹ r ẹ awọn ẹranko, a ngbọ hiho wọn, nwọn pọ, nwọn nlọ si Ipade a yara sare gun igi, ha! ẹnu ko gba irohin. Igbin ibẹ tobi to odo (ohun ta fi ngun iyan), Ijapa ibẹ si tobi to aja ati pe ẹsẹ wọn mẹrẹrin ni nwọn fi nrin. Oju wa ri nkan laleṣojọ yi. Laipẹ nwọn ru Ọba wọn de. Erin si ni (Agbọnrin alare) gun, nigbati o si de ọdọ wa, o gbọ orun wa, o si paṣẹ ki nwọn mu wa, w e r e awọn erin meji ti na imu wọn, nwọn si gbe wa ni ọkọkan ayafi Arikutaku ni nwọn ko ri nitori on ko gungi. Iho ni o wọ.

Nigbati nwọn gbe wa de ibi ipade wọn, Inaki ni nwọn fi sọ wa, nwọn si de wa mọ i g i, ti o wa ni ọkankan ibi Ipade wọn. Nigbati Ipade wọn si bẹrẹ, ohun ti mo kọkọ ṣe akiyesi ti o si jẹ iyalẹnu fuu mi ni pe ohun ti nwọn danu le ni pe ọna t'awọn yio gba t'awọn na yio fi gbogun ti awa enia ti awọn yio si ṣegun wa. Ẹta ni o damọran yi, awọn ẹranko yoku si gbee lẹsẹ, nwọn lawọn fara mọọ, ariwo wa nta gee. Nikẹhin nwọn pinnu lati yan awọn ti yio sọrọ lori aba yi

Ẹkun ni nwọn kọkọ yan wipe ki o sọrọ. O ni, ẹ ku joko ẹnyin ẹlẹgbẹ, ẹgbọn ati aburo mi, ọrọ ti a npero rẹ yi, o jẹ ohun ti o yẹ ki a sapa wa si gan ni, nitori pe jẹjẹ wa ni a joko ti awọn abirun lori wọnyi (o na ka si wa) wa nyọ wa lẹnu, mo si rope bi a ba pa ero pọ a o lọ ba wọn a o si pa gbogbo wọn. Eyi ti o k u k u mọ ekanna fi ja wa ninu wa, eyi ti o si mọ iwo fi ja wa pẹlu. Mo da ni aba ki a lọ ba wọn o.

## OWE ILẸ YORUBA

Lati ọwọ:- RAMỌNU TỌLANI BỌLỌRUN-O-PAN
No. 402 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

1 Bi ọmọde ba subu a wo iwaju, bi agbalagba ba subu a wo ẹhin.
2 Bi iyawo Ọlẹ ba dagba tan Olowo ni gbe e.
3. B'ọkọ rokun, rẹsa afabọ f'elebute
4 Bajọsakala ajẹ ọsakala, bajẹ osokolo a jẹ osokolo, ọsaka-nsoko ko yẹ ọmọ enia.
5 Enia ko fẹ ni fọrọ bi ko ṣori ẹni.
6 Ebi ki wọnu ki ọrọ miran wọ ọ.
7 Ẹni fojudi oku ana, Ẹbọra a bọ ọ laṣọ.
8 Onile ọwọ ọtun ko fẹ ni fun rere, imọran ika ni tosi ngba, kẹnimọni ni tọkankan ile.
9 O ogun ti a ko fi owo ṣe ẹhin aro lo ngbe.
10 Oju ni r'oju sanu, bi Ọni ba gbe ohun ọdẹ rẹ a pajude.
11 Okete bayi niwa rẹ, o ba Ifa mulẹ o da Ifa.
12 Ọrọ ti Ọlọgbọn ba sọ ẹnu asiwere ni a a ti i gbọ ọ.
13 Ewu logbo, irungbọn lagba tubọmu lafojudi.
14 Ọdalẹ ba lẹku, ẹni dalẹ a ba ilẹ lọ.

## FA ỌGBỌN YỌ

Lati ọwọ:- MỌSHUDI ỌLADUNWO
No. 94, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

1 NREI
2 IWDAO-EOK
3 JWUẸLAA
4 OUKEBTAA
5 GRSHOOO
6 SHOMỌGBỌO
7 NBDIAA
8 IMOORLSUI
9 OLWANDUO
10 ỌỌNMỌNỌM
11 EZEBNERE
12 NUBLGOA

## Ẹ NLẸ O! ẸNYIN ỌMỌDE L'ỌKUNRIN ATI L'OBINRIN

Gbogbo ẹnyin Ọmọde l'Ọkunrin ati l'Obinrin ni mo ki pata pata, ẹ ku ọjọ mẹta, mo lero pe gbogbo nyin ni o mura si ẹkọ nyin ẹ maṣe binu pe ẹ ko ri ọrọ mi ka ni ọsẹ tokoja. Ẹ si ku ipalẹmọ Idanwo nyin to nbọ yi o. Oluwa yio ran gbogbo nyin lọwọ, Ẹ mura si iwe nyin dada o.

Mo bẹ ẹnyin ọmọde, ẹ ye ma mu siga, nitori mo ri pe o ṣẹ fẹ ma di aṣa fun ẹnyin Ọ m ọ d e. Ojojumọ ti mo ba si nrekọja lọ ni titi l'Eko ni mo ma nsaba pade awọn ọmọde ti o ma ngmu Siga. Ẹ ye mu siga mọ, ko dara fun nyin lati iwoyi lọ. Ẹ jọwọ ẹ fi Siga mimu silẹ ki ẹ kọju mọ iwe nyin, arun buruku ni siga nfa o, o le ma tete jade ṣugbọn ti o ba ya yio jade si nyin lara.

O digba kanna o, ẹnyin Ọmọde.

Emi ni,
LATIFU BABALỌLA

## ITUMỌ FỌGBỌNYỌ

1 ERIN
2 AWODI-OKE
3 AWUJALẸ
4 ABEOKUTA
5 OSHOGBO
6 OGBOMỌSHỌ
7 IBADAN
8 ORIMOLUSI
9 ỌLADUNWO
10 MỌNỌMỌNỌ
11 EBENEZER
12 BALOGUN

Ẹnikẹni ti o ba nfẹ imọran ti o d ja nipa gẹgẹbi a ti nṣe ohun ti awọn npe ni Insurance ki o lọ ri:-

Awọn Ọgbẹni. T. A. BRAITHWAITE

(Insurance Brokers) & Co

5, Williams Street
P. O. Box 785, Lagos Nigeria.
Telephone 21550, 21559

Awa ni oniṣowo ti iṣe Aṣoju fun gbogbo awọn Ẹgbẹ oniṣowo Insurance Oriṣiriṣi ni ohun ti a le ṣe Insurance le lori, diẹ ninu wọn ni wonyi:-

A le fi ẹmi ara ẹni ṣe e.
A le fi dukia ẹni ṣe e.
A le fi mọto ẹni ṣe e.
Ki jamba maṣe ṣelẹ sini.
Ki ina maṣe jo dukia ẹni.
Tabi ki ọkọ ẹni maṣe baje
Gbogbo a w ọ n Oniṣowo Insurance ni a nṣe Aṣoju fun.
Lọfẹ ni a nfi ọna bi a ti nṣe ohun awọn to ba fẹ, yio si tẹ Oluwarẹ lọrun.

# Aiye yi ko ṣe tẹle, Iṣina Lo wa Nibẹ

Lati Ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE

Mo ki gbogbo ẹnyin Olugbọ ọrọ mi, Oluwa ko ni fi Iku ojiji pa gbogbo wa o, Amin. Ẹnyin enia Ọlọrun, Ẹ maṣe tẹle Ọmọ Araiye, Nitoripe Iṣẹ Iṣina ni gbogbo nwọn nṣe, Bi Ọmọ Araiye ba yo tan, nwọn a ma wipe ko si Ọlọrun! Amu ni ṣina ni ọmọ Araiye, Iku ni Igbẹhin enia, Akitan ni Igbẹhin Onjẹ, Okun ni Igbẹhin Omi, Ofo si ni Igbẹhin Aiye, Ṣugbọn Iye, Ayọ, Alafia, ni Igbẹhin fun awọn ti o ba gbẹkẹle Oluwa, bẹni yio si dara fun wọn.

Ọrẹ aiye yi jẹ Iṣina, bi o ba dara fun ọ tan ọrẹ aiye yi yio fẹran rẹ ṣugbọn bi o ba di ẹhin tan tabi ti nwọn ba kuro lọdọ rẹ tan n w ọ n a ma hu i w a Ibajẹ si ọ, Nitorina Ẹnyin enia Ọlọrun, Iṣina ni Ọrẹ Aiye yi jẹ Jesu Kristi nikan ni ọrẹ Otitọ ati Olododo.

Nitorina ẹ maṣe gba Ọrẹ kan gbọ, Ẹ ma si ṣe gbẹkẹle Amọna kan, pa Ilẹkun ẹnu rẹ mọ fun ẹniti o nsun ni ọkan Aiya rẹ, ti a ba lọ sinu iwe mimọ a o ri ka ninu iwe MIKA ORI 7. ẸSẸ 5.

Aiye yi ko ṣe tẹle Iṣina lo wa nibẹ bi iwọ ba si ni owo lọwọ Aiye yio si ma ba ọ wa ọna ti owo na yio fi kuro lọwọ rẹ.



Nwọn ko ni bẹru Oluwa Ọlọrun bi iwọ ba yo tan ọmọ araiye yio si ma a wa ọna ti iwọ yio fi t u n ma a wọ Akisa Aṣọ.

Ẹnyin ọmọ araiye kini mo ti ṣe nyin MIKA ORI 6. ẸSẸ 3. Ẹnyin Ọmọ Ọlọrun ẹ maṣe fi inu yin han aiye ki ọmọ araiye ma ba mu yin ṣina Ọlọrun nikan ni ki ẹ fi inu yin han mo bẹ nyin Ọ l o r u n nikan ni o le ṣe Amọna Ẹda

Mo ki gbogbo ẹnyin Ọmuti Oluwa ko ni jẹki ẹ ku si Tọmbila Amin Egbe ni fun ẹniti o fi ohun mimu fun aladugbo rẹ ti o si fi ọti lile rẹ fun un o si jẹ ki o mu amupara pẹlu, ki iwọ ba le wo Ihoho rẹ nitoripe agbere ni awọn Ọkunrin ti o ma a lọ si Ile ọti (HOTELS) HABAKUKU ỌRI 2. ẸSẸ 15.

Enia ti o ba ti jẹ Imọle tabi Alhaji tabi Onigbagbọ ti o ba si nmu ọti emi eṣu koiti kuro lọkan rẹ, gbogbo ẹnyin ọmọ Ọlọrun. Ẹ ba mi ṣe amin si Adura mi yio

Ọlọrun Eledumare Ẹlẹda Ọrun on Aiye mo bẹbẹ ṣanu fun mi ti mo ba bimọ Obinrin, Oluwa jọwọ maṣe jẹ ki o mọ ọna ile ọti ati ile oni siga bi ti ọpọlọpọ ninu awọn Ọmọ Eko.

Oluwa jọwọ ti mo ba si bimọ Ọkunrin maṣe jẹki o ṣe Ọga (Manija) kẹni mani oloju kokoro ati Ọmuti Oluwa jọwọ ọmọ ti ko ni gbọ tirẹ maṣe jẹ ki o ya sọdọ mi o ọmọ ti ko ni mọ ọna Ile Ọlọrun ti yio ma lọ si ile ọlọti Baba majẹki o ya lọdọ mi o.

Awọn Yoruba ni "Were dun wo, ṣugbọn ko ṣe bi L'ọmọ". Bẹni inu baba asiwere ki dun rara, nitoripe were ni ọmọ rẹ. Ki Ọlọrun majẹki iru rẹ o ya sọdọ gbogbo wa. Bẹni ọmọ ale ko ni wọ ijọ enia Ọlọrun lati iran kẹta, enia rẹ kan ko ni wọ inu ijọ enia Ọlọrun (DEUTORONOMI ORI 23, ẸSẸ 2).

---

# Ẹniti o gbin Ewe Taba Igbo Sẹhin kule rẹ wẹwọn Ọdun meji

ENUGU.- Ọgbẹni G. C. Nkemena, Adajọ Kotu giga Enugu ṣe Idajọ pe ki Ọdaran kan, Paul Uwaghue, eni ogun ọdun lọ si ẹwọn ọdun meji nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa mu fun wipe o gbin ewe taba Igbo si ẹhin kule rẹ.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣejọ niwaju Adajọ so pe, nigbati awọn nwa ẹkan kakiri si A d u g b o na, ni a w ọ n ri igi ewe t a b a Igbo ninu ọgba kan, nigbati awọn si bere, ni awọn so wipe Ọdaran na lo ni.

Siwaju eyi, awọn Ọlọpa ṣe apejuwe Ọdaran na wipe ko ni iṣẹ kan ti o nṣe e, nigbati o si gbin awọn ohun ọgbin si inu ọgba rẹ o gbin ewe taba igbo si arin wọn, nigbati Adajọ bi ọdaran na lere wipe, "Kini tirẹ ti jẹ? o gba wipe on jẹbi ni Adajọ ba fi ṣe idajọ gẹgẹ bi a ti wi siwaju.

---


## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such Scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st July, 1962 to 31st December, 1962, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa area.

A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed tender form should thereafter be returned to the Secretary in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Friday, 20th July, 1962.

The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tenderer, who, upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

During the six month period indicated, the successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap is made available for sale (with the exception mentioned above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No. 729
4th July, 1962.

# IMỌRAN FUN AWỌN OBINRIN

Lati owọ:- IYAFIN WULEMỌTU AMỌPE
Alias:- OLOTỌ OBINRIN.

Ẹ karọ o, Olotu ati ẹnyin alabaṣepo re, gbogbo nyin ni mo ki ẹnyin onkawe mi, ẹ ku ọjọ mẹta ti a ba ṣa ti rira ẹni pẹ, ẹ ku a ti, laki ara eni.

Ẹ si ku arọda ojo yi. Ani ki a ma fẹku o wa sọ di ojojumọ mo si tun ki gbogbo ẹnyin onkawe wa, pe Ẹ o jire.

Ọrọ ti mo ma ba yin sọ loni. Ni Imọran lori awọn Obinrin ti o ntọ Ọmọ lọwọ Nigbati ọpọlọpọ awọn Obinrin ba ntọ ọmọ lọwọ wọn ko ni fi ara balẹ lati toju ọmọ wọn ti nwọn yio fi tun ma ba ọkọ wọn tage ọpọlọpọ obinrin ni ko mọ wipe bi Obinrin ba ti ba awọn Ọkunrin tage bayi nṣe ni ara wọn ma ngbona, wọn ko si ni boju wo ẹhin lati wo pe baya Iyawo awọn ntọmọ lọwọ, awọn mejeji a si ma ba Iṣẹ lọ.

Awọn ti wọn ba ṣe bayi Ọmọ ti nwọn ntọ lọwo ko ni, ni Ilera to ati wipe oniruru arun ati ailera ni yio ma ṣe Ọmọ, ti ọmọ na ko ba ni onitọju dada o le fi be di ẹni ọrun lojiji.

Ọpọlọpọ ni awọn Obi ti nwọn ti di alailọmọ nipa ona yi.

Nitorina, ẹnyin Obinrin ẹ maṣe g b a awọn Ọkunrin laye nigbati ẹ ba ntọ Ọmọ lọwọ ẹ maṣe jẹ ki nwọn de ọdọ nyin rara ohun gbogbo ti a le ni ọmọ loju ko si eyiti oju ọmọ lọ bi a logun eru ki a yawọfa ọgbọn ọjọ ti a ba ku ọmọ n Adele ki Ọlọrun jẹ ki ọ sọ gbẹhin gbogbo wa o.

Ẹnyin ti o si jẹ wipe ẹ ti nṣe irufẹ nkan bayi ẹ jawọ kuro nibẹ awọn ti o ti bimọ ki Ọlọrun ba wa wo wọn, awọn ti koibi Ọlọrun o pese ọmọ fun wọn, awọn ti o si wa nipo Abarameji Ọlọrun yio sọ wọn kalẹ pẹlu Ayọ a o gbohun Iya a o gbọtọmọ.

Ipade di ọsẹ to mbọ a o fi Ire pade o.


GBANGBA DẸKUN KEDERE BẸ WO!




OLUBORI EGBOGI "IKỌ"
THIOLYPTINE

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbi-rọbi ka le ṣe iwoṣan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranse ti nwọn npe ni Thiolyptine Ojulowo hanu-haun, atamatẹṣe egbogi fun Ikọ Fere, Ikọ tutu, Ikọ ọna-ọfun, Ikọ igba-aiya, Ikọ-lile, Ikọ ti o ma nmu ki enia ma tu Kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu ki enia tu pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi Thiolyptine wo, iwọ na yio ri iyatọ lara rẹ ni kiakia. Igba aiya tabi ona ọfun rẹ ti o ma ahe yo duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata. Iwọ yio ma jẹun diaradara. Iwọ yio si ma sun fọn-fọn pẹlu alafia ara.

Bere egbogi yi ati awọn oriṣiriṣi egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:— Price 10/6d Postage 2/6.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878


# YẸ IRAWỌ RẸ WO

Nitori ki a ma ba jiya ni a ṣe nya majiya l'ọfa ati wipe nitori ki a ma ba ṣe abamọ gbẹhin ọrọ wa. Yẹ irawọ rẹ wo, nitoripe ogun agbọtẹlẹ ki pa Arọ.

**Aquarius** (Jan 20-Feb 18) Ma ṣe sare nipa iwe kikọ. Bi iwọ ko ba ṣe ara rẹ, irohin ayọ yio tẹ ọ lọwọ

**Pisces** (Feb 19-Mar 20) Iwọ yio ri igbadun lọsẹ yi, ara rẹ yio si le dada, ṣugbọn ma ṣe ba ẹnikan ti o fẹran jiyan

**Aries** (Mar 21-Apl 19) Ninu ọsẹ yi, iwọ ko tilẹ ni mọ kini ohun ti o nṣe ọ tan. Iwọ yio ba Ale rẹ sọrọ ifẹ, kio si sọra rẹ nipa ọrẹ na.

**Taurus** (Apl 20-May 20) Nigbati o ba kọkọ ji ni owuro Ọrọ ohun ti o ṣe paaki ni ki o kọkọ ma moju to. Arẹ yio si mu ọ gẹgẹbi otu tu lọwọ irọlẹ.

**Gemini** (May 21-June 20) Ọkan rẹ nfẹ isimi, bi o ba si kọ lati simi, iwọ yio ri ere aigbọran jẹ.

**Cancer** (June 21-July 20) Iwọ yio ri ere pupọ jẹ lọsẹ yi, Iwọ yio si gbọ irohin ayọ kan pẹlu. Ṣugbọn ọrọ kan wa ti o mbi Olufẹ rẹ ninu.

**Leo** (July 21-Aug 22) Ọrọ ibinu kan wa larin iwọ pẹlu Olufẹ rẹ, ohun ti o fa sababi ọrọ na ni pe iwọ fihan sode.

**Virgo** (Aug 28-Sept 22) Ọrọ kan ti o nrinrin rẹ lọwọ yio moke bi o ba fẹ sun ni alẹ, ibiti o nfi ẹsẹ si ni kio ko ori si.

**Libra** (Sept 23-Oct 22) Akoko owurọ yio dara fun ọ maṣe gbe lẹẹ pamba kan dani lọsan ninu ọsẹ yi, nṣe ni ki o rinrin faji lọ.

**Scorpion** (Oct 23-Nov 21) Ọsẹ yi dara fun ọ lati ri Olufẹ re, ṣugbọn kio ṣọra rẹ kio ma ba ko arun.

**Sagittarus** (Nov 22-Dec 21) Ọsẹ yi dara fun ọ lati ri Olufẹ rẹ, iwọ yio gbọ irohin aladun kan pẹlu maṣe jafara.

**Capricorn** (Dec 22-Jan 19) Iwọ yio ri Alejo kan ti o mu irohin aladun kan wa fun ọ, gbogbo iṣoro ti o wa fun ọ ni yio fọlọ. Lọ kesi awọn Ẹbi rẹ ati awọn Aladugbo rẹ pẹlu.

# Ọmọ titun Alejo Aiye!

Irohin ko to afojuba ni ti Ikomọ jade Ọgbẹni Lawal Bello ati Iyawo re Ṣifawu ti Ọlọrun fi ta wọn lọrẹ ni ọjọ k a r u n oṣu kẹfa ọdun yi ni Nọmba 3, Ọrẹmẹrin Street Bariga.

Nigbati o ti ku ọjọ mẹrin ni awọn ero ti bẹrẹsi de lati Esiẹ Offa Oro Orimi, Ijọmu Afin, Mushin ati bẹbẹ lọ. Nigbati Ọjọ Ọmọ kiko pe awọ ọmọ Ẹgbẹ Kajọla tiṣe Ẹgbẹ baba ọmọ fọmọyọ lọjọ na Alfa Musa ni o ṣe suna ọmọ na ni Ọna ti Musulumi.

Alfa yi lo ma a nṣe suna ọmọ fun gbogbo awọn ọmọ Esiẹ ni Agbegbe Eko. A si sọ Oruko ọmọ na ni Bisiriyu Ayinda Lawal

Baba ọmọ na Lawal Bello ati Ṣifawu Iya Ọmọ na ati awọn Ọmọ Ẹgbẹ Kajọla pẹlu gbogbo awọn Alabaṣẹyẹ lijọ na junmọ njo pa pọ bi kokoro ni, irohin ko to afojuba ni ẹyẹ ati adun ikomọjade na, orisirisi onjẹ adidun, ọti, obi ati siga ni Baba-ọmọ na fi tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun

Nigbati inawo, na bẹrẹ nṣe ni gbogbo Ilu bẹrẹsi rọ kẹkẹ fun inanwọ ọjọ na. Ni deede agogo mẹrin Irọlẹ ni ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Kajọla ti pe sanmusaomu pẹlu onilu wọn. Awọn Ẹgbẹ na wa bẹrẹsi jo yi gbogbo Ilu Bariga ka pẹlu aṣọ wọn titun ti nwọn da. Ọgbẹni Lasisi Onilu Ẹgbẹ Kajọla fi kọkọrọ ilu rẹ dara ni ọjọ na; faji ọjọ na bua-aya, o le gongo

Diẹ ti aiye wa fun ninu awọn enia Jankanjankan ti o wa s i b i isọmọloruko na ni wọny:- Debora Ọmọrin-Ọla Awawu Bello, Ezekiel-

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE

## IWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- Afolabi Ojelabi

# OWO

Ọmọ Ori Ade
Bọmọde ba nṣaiya gbangba
Sohun tagba ko to gbe
Bọmọkekere ba nṣowọ fẹnfẹ
Sohun tagba ko gbọdọ dani
Ko ya laju, owo ni ngbee lọ
Bọmọde lowo lọwọ, a gbagbe ọjọ ori
Bọmọde ni Kudi a gbagbe olore
A wo ọmọde bi ẹni pe Oluwa ko da
A wagba bi ẹni pe ko i ti kuro lawujo
Owo, owo, owo.
A ṣoro ni lọwọ bi wara Kiniun
A ṣoro di sọwọ bi iṣo alabahun
Bowo bagba rẹ, a sọ ọ di ọmọde
A dalafẹ a dọmọge ti Wudia nfẹ
Bowo bọmọde rin
Adẹni agba nforibalẹ fun
Owo ti nsọ abaro d ọ g a ọgbọn
Ti nsọ agba di itiję ọmọge
Ohun lo nfọ ile
Ti o nsọ ilu dahoro
Owo ti nsọ talaka di baba ijoye
On lo nmu ọkanjuwa sọ'le nu bi oko
To nmu ojukokoro tale baba
ṣe ntori ọla
Ọmọ ori Ade
Owo ni gbongbo ẹṣẹ
Ọgọrọ enia lo tori owo ran ọmọ enia sọrun
Pupọ lo tori owo di Oṣelu
Ti n w ọ n nfi iya jẹ awa mẹkunnu kiri
Eni lowo niwọn ko mọ iyin
Eni ko lowo ti ko jẹ gbese
Ko mohun Oluwa ṣe fun on
Lagbaja tori owo, o fọmọ fọba
Tamẹda tori owo o ta ilẹ
Alaimọkan tori owo, o ntaka si wa
Tani ko mọ pe owo ni gbongbo ẹṣọ?
Bo lowo lọwọ aiye a ri ọ
Boko lowo lọwọ nwọn a ju ọ nu
Olowo lọrẹ Ebi
Ailowo lọwọ ṣẹgbọn nisan
Aini kudi o ju ori fifọ lọ
Ṣugbọn owo gbigbona ni opa ni
Owo ẹṣa ni nrun ile
Owo adanu ni nfọ ilu ẹni
Benia tori owo gbin buruku
Bowo ba de ko ni le ma
Benia tori owo h uwa ika
Bo pẹ titi a jiya oro
Bo pẹ titi ọjọ atisun a de
Bo pẹ titi a tun di ilẹ pẹlu ọwọ ofifo.

## IKEDE PATAKI

Fun awọn O n i b a r a ti awọn fi owo silẹ fun awọn Iwe wa ti o tan laipẹ yi. Inu wa dun lati sọ fun wọn pe a ti ni won lowọ nisisiyi.

Iwe Aṣiri Ọba Solomon 20/-, Iwe Aṣiri Ọba Dafidi 20/-, Iwe Kẹfa-Keje-Kejọ ati Kesan Mose 20/-, Lilo ati Agbara Psalm 5/6d, dozen rẹ jẹ 54/-, Iwe Ala 5/6d dozen rẹ jẹ 54/-, Iwe Adura Pelu Orukọ mimọ Jehovah 5/6d, dozen rẹ je 54/-, Iwe Adura Aṣiri Fun Awọn Ẹgbẹ Aladura bi Ijọ Kerubu ati Serafu 5/6d, dozen re jẹ 54/-, Iwe Iwoṣan Adahunṣe 2/-, Iwe Ilans Pool L'ede Yoruba 2/- ati ogunlọgọ ohun miran. Kọwe si MANAGER:

232, HARBERT MACAULAY STREET,
YABA, NIGERIA.

## IGI YA PA ỌKUNRIN KAN

IBINNI:- Agbọṣọ-gbanu ni irohin iku Ọgbẹni Benson Okeke ẹni ọdun marunlelaadọta, ti ngbe abule Ashana ni agbegbe Asaba.

Ọgbẹni O k e k e dagbere wipe on nlọ si oko rẹ ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi nigbati o si ku diẹ ki o de oko rẹ ni igi kan ba ya ni ojiji ti o si ya pa Ọkunrin na mọlẹ patapata.

Nigbati a w ọ n enia rẹ gbọ nwọn lọ si ibẹ lati lọ gbe Oku rẹ wale, nwọn gbẹlẹ ni ki nwọn to ri oku rẹ gbe w a l e.

Ki Ọlọrun ma jẹ ki a rin ni ọjọ ti ebi npa ọna o.

## OKU KAN JINDE

OPOBO:- Ariwo ta gee, okiki kan ku u nigbati obinrin kan, Mary Akpan Uko, ẹni ọgbọn ọdun ti o si ti ku tun jinde kuro ninu oku ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi.

Gbogbo awọn enia ti o wa sibi Iṣinku Obinrin na lo fi ọsẹ fẹ e nigbati nwọn ri oku ti nwọn fẹ sin ti o dide joko lojiji nibiti nwọn ti nṣọkun ti oku na si bẹrẹ si mi, ti o si yaju kodere, ti o si nwo gbogbo awọn ero. Igbẹ lafẹwe oko lafẹ lasa, ọrọ na di bi o ko lọ ki o ya fun mi, ti olukuluku wọn si bẹrẹsi salọ, nibiti awọn miran ti nsalọ nwọn ṣubu lulẹ, elomiran dajubolẹ.

Ọkọ Obinrin na, Ọgbẹni Ufi Unwa Uko, ẹni ọdun marundinladọta sọ wipe iyawo on ti ku on si ti ṣe itoju rẹ ki on to lọ sọ fun Padi Ṣọọṣi Aguda ilu on, Essene fun eto isinku. Bi on si ti ra posi tan, ti on si gbe e dele, ti awọn enia si bẹrẹsi ṣọkun ti awọn si npalẹmọ lati gbe oku iyawo on sinu Posi lati lọ sin, lojiji ni on deede ri awọn enia ti nwọn bẹrẹsi sare jade, ti nwọn si nṣubulu ara wọn.

Nigbati on si de inu ile ni on ba ri iyawo on ti o ti ku tito joko tete nibi ti awọn enia tẹẹ si. O si bẹrẹ si tu awọn aṣọ ti awọn fi tọju re ti o si n b e r e lọwọ on wipe "Kini awọn enia ti o duro wọn nwa, ti nwọn fi pọ to bayi?" on si sọ fun un.

Obinrin ti o ku, ti o si jinde, na sọ wipe on ko mọ wipe on ti ku, on ko si mọọ, nkan ti o ṣelẹ si on nigbati on ti ku, ati pe on ko mọ pe on ti ku, ṣugbọn on gbagbọ wipe on ku nitotọ nitoripe on ri ọpọlọpọ awọn enia ti o yi on ka nigbati on yaju ati wipe awọn enia ti o nsọkun na si bẹrẹsi salọ.

O ni ara on ko ti ya fun nkan bi ọdun marun sẹhin ọkọ on si ti ṣe eto lati gbe no lọ si Ile Iwosan fun itoju.

Ọdun kẹriadinlogun ti Mary wọ leko niyi o si bi ọmọ mẹrin fun Ọkọ rẹ.

* Adajọ Kẹta Ijọba Ibile Ibadan ju Ọdaran obinrin kan Atinukẹ Babakẹmi si Ewon oṣu mẹta nitoripe o ti gbe rẹ £12 lapo Iyalẹ Florence Ekundayo nigbati o nra nkan loja Dugbẹ Ibadan, ọdaran na ni on ko jẹbi

BERE EGBOGI PATAKI YI TI WỌN NPE NI:-


# "Figurana"

Jẹ ojulowo egbogi ti awọn Jamani ṣoṣe ṣe iwadi rẹ fun awọn ti o ra sanra tabi ti o ba "TOBI" ju lati ma mu ki wọn le fọn tabi jọn ku lai si wipe wọn ma ka ewọ oṣiṣẹ ti nwọn o ma jẹ rara bẹ si ni ko lewu ni lilo fun enia rara.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupọju ki nṣe ohun ti o dara rara, ọpọlọpọ a m o d i ni o nko ba enia, bi Lakuregbe, Aikolo gbera ni ilẹ bi o ba joko, Aya lilu kiki tabi jija nigbakugba aikole mi kọnlẹ daradara, ara wiwo tabi wiwuwo, Eemi mimi họ-họ ati orisirisi amedi omiran pẹlu.

Ṣa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ na yio ri ayipada ati Alafia ti yio de si ọ. Bere ni Ṣọbu awọn Olori elegbogi Jamani ni igboro ilu Eko:-

ADEDUN CHEMISTS
WAKEMAN STREET YABA.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigerian. (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278·

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878


*Printed and Published by:— MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos Olotu: E. A. Adeniji. 24, Oliyide Street, Odi-Abere Mushin.*